# Ìfètòsọ́mọ Bíbí Onísàáná Apá Tí Ó Ní Èròjà Nínú Ọ̀pá Tẹ́rẹ́ Méjì (Jadelle)



**Àlàyé nípa rẹ̀:**

- Àwọn ohun èlò onísàáná apá yìí jẹ́ ọ̀pá tẹ́rẹ́ méjì (tí títóbi wọn kò ju bíi igi ìṣáná lọ) tí a má ń fi pamọ́ sínú awọ ara ní agbègbè òkè apá wa.
- Ó ma ń dènà oyún níní fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún tó tó ọdún márùn-ún.
- Akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ ìfètòsọ́mọ bíbí ló gbọ́dọ̀ fisí apá tàbí yọ ọ́ kúrò.
- Kò léwu fún àwọn obìnrin tó n´fọ́mọ lọ́yàn lọ́wọ́.
- O lè gba ohun èlò yìí láàrín ọjọ́ méjì tí o bá ti bímọ.
- Kò dènà ìbálòpọ̀ àti kòkòrò HIV

**Bí ó ti lè dènà oyún níní:**

Ní lílò fún ọdún kan àkókò, óseése kí ó dín díè ní ẹyòkan nínú ọgọ́run obìnrin kí ó lóyún (oyún kan nínú ọgọ́run obìnrin)

**Bí óṣe ń ṣiṣẹ́:**

- Akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ ìfètòsọ́mọ bíbí yíò fi onísàáná apá yi sí abẹ́ awọ ara obìnrin ní tò sí òkè apá níbi abíyá.
- Onísàáná apá yì yíò ma tu èròjà ara (progestin) díè díè sínú ara.
- Èròjà ara (progestin) yíò mú ikun tí ówà ní enu ọ̀nà ilé ọmọ kí ó ki, èyí yí ò dènà kí àtò okùnrin má lè wọ ilé ọmọ.
- Èròjà ara yí kí yíò jẹ ki obìnrin kì ó yé ẹyin tí ó pọ́n (yíyé ẹyin làti nínú àpò ẹyin obìnrin)

**Àkíyèsí pàtàkì:**

- Ohun èlò onísàáná apá yìí ń sisẹ́ dáradára àti pé ó jẹ́ ìlànà ọlọ́jọ́ pípẹ́
- Kò fa ìdíwọ́ kankan fún ìbálòpọ̀ lọkọ laya

**Àkíyèsí:**
**Ó ṣeéṣe ki isẹ onísàáná apá yí dínkù fún obìrin tí ó sanra (tí ìwọ̀n rẹ̀ bá tó ju àádọ́rin kìlógíráàmù lo fún Jadelle àti ju àádọ́rùn-ún kìlógíráàmù fun Implanon).**

**Irú àwọn obìnrin yi ma nílò láti rópò onísàáná apá yí kí ó tó di odún mẹ́ta (odún mẹ́ta fun Jadelle ati odún mẹ́jì fun Implanon)**

**Ìlànà yí kò sí fún ọ bí:**

- O bá ma ń rí ẹ̀ jẹ̀ ní ojú ara tí a kò lè sàlàyé.
- O bá ní kókó nínú ọyàn (jejere) tàbí ẹnikéni nínú ẹbí rẹ ti ní kókó nínú ọyàn rí sí ọdún máàrún sẹ́yìn
- O bá n lo ògùn fún gìrí tàbí o ń lo rifampicin (nítorí ó lè dí ìfètòsọ́mọ bíbí yí lọ́wọ́ láti ṣiṣẹ́)
- O bá ní ẹ̀jẹ̀ dídì, àrùn tí ó níse pẹ̀lú ẹ̀dọ̀ àti ẹ̀dọ̀fóró

Get it together
KNOW. TALK. GO.



**Àwọn ipa tó le ní lára:**

1. Ó lè ṣàkíyèsí àwọn àyípadà ni ǹkan oṣù, àwọn ohun tó lè fojúhàn nì yàn yí:
    - Kí ǹkan oṣù máa ṣàn/kí ọjọ́ rẹ̀ kéré tàbí kí má ṣe ṣégeṣège fún ọjọ́ méjọ.
    - Kí ǹkan oṣù má ṣe dédé tàbí kí ó má wá rárá.
2. Ó lè fa orí-fífọ́, inú rírun, ọyàn rírọ̀ tàbí ìnira pẹ̀pẹ̀pẹ́ .

Àwọn àmì yí wọ́pọ̀. Eyí kìí se àmì àìsàn àti wípé ó yàtọ̀ láti obìnrin si obìnrin.

**Bí aṣe lè lò ó:**

- Akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ ìfètòsọ́mọ bíbí yíò fún o ní abẹ́ré lápá, láti dènà ìrora. Yíò wá fi onísàáná yìí sí abẹ́ awọ apá obìnrin ní dédé ibi abíyá
- Gbogbo ṣíṣe èyí kò ju ìṣẹ́jú díè lọ. O ó lajú láti rí ohun tí wọ́n se. Ó ṣeéṣe kí ó dà bí ẹnipé ǹkan kan ẹ́  lára, tẹ apáàrẹ rẹ tàbí ìnira díè nígbà tí wọ́n bá ńgbin ohun èlò náà sí apá.
- Léyìn bí abá ṣetán, gba àwọn ìtọ́nisọ́nà yìí lọ́wọ́ akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ ìfètòsọ́mọ bíbí:
    - Ọjọ́ tí a gbìn onísàáná náà, oṣù àti ọdún tí á ò yọ́ kúrò tàbí fi òmíràn si i tí ó bá wù ó làti tẹ̀ síwájú ìlànà yí.

**Rántí wípẹ́:**

- Má ṣe jẹ́ kí omi kán ojú ibi tí wọ́n fi ohun èlò onísàáná náà sí fún ọjọ́ mẹ́rin
- Ó ṣeéṣe kí apá náà ro ẹ́  fún ọjọ́ díẹ̀
- Ó ṣeéṣe kí ojú ibi tí wọ́n fi ohun èlò onísàáná náà sí wú tàbí dégbò díẹ̀. Bó ṣe yẹ kó rí nìyẹn. Á lọ láìgba ìtọ́ju kankan.

**Padà lọ sí ilé ìwòsàn bí:**

- Ojú ibi tí wọ́n fi ohun èlò onísàáná náà sí bá dẹgbò, ó ń se ọyùn tàbí ó pọ́n tí ó ń ro si ni ojojúmó láì jiná
- O bá ri kí ohun èlò onísàáná náà ń yọ síta
- O bá ní ìbéèrè tàbí o ní ìṣòro kankan
- Àsìkò bá tó láti pàrọ̀ ohun èlò onísàáná náà
- O bá fẹ́ yọ ohun èlò onísàáná náà kuro
- O bá ti sanra jù.
- Ohun èlò onísàáná kò lè dènà oyún tí ìwọ̀n rẹ bá ti kọjá àádọrin kílò lọ (70kg)
- O bá dojú kọ ìṣòro àìlera kan
- O bá lérò pé o ti lóyún.

This material is adapted from a similar material by Society for Family Health (SFH)